# AWỌN ẸKỌ JESU LORI JÍJẸ́ ỌMỌ-ẸYIN

## Matteu 17:14-21; Luku 9:51-62

### ẸKỌ 115 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́ bi wóro irúgbin mustardi, ẹnyin o wi fun oke yi pe, Ṣi nihin lọ si ọ̀hun, yio si ṣi; ko si si nkan ti ẹ ki yio le ṣe" (Matteu 17:20).**

**I Iwosan Ọmọkunrin ti O Ni Ẹmi Yiya-Odi**

1. A n yọ ọmọkunrin kan lẹnu nitori o ni ẹmi eṣu, Matteu 17:14, 15; Marku 9:14-29, Luku 9:37-42
2. Agbara awọn ọmọ-ẹyin ko to nitori aini igbagbọ, aawẹ ati adura, Matteu 17:16-21
3. Jesu mu ọmọkunrin naa lara da, Matteu 17:18

**II Awọn Ara Samaria Kọ Kristi**

4. Awọn ara Samaria ko gba Kristi, Luku 9:51-53; Johannu 4:9
5. Jakọbu ati Johannu fẹ ki a pa wọn run, Luku 9:54; 2 Awọn Ọba 1:10, 12
6. Jesu wa lati gbala, ki i ṣe lati parun, Luku 9:55, 56, 19:10

**III Awọn Ọmọ-Ẹyin Onilọwọọwọ Ọkàn**

7. "Ọmọ-enia ko ni ibi ti yio fi ori rẹ̀ le" Luku 9:57, 58; Matteu 6:25
8. Ipe Kristi ni o ni lati gba ipo kinni, Luku 9:59, 60; Matteu 6:33
9. Bi o ba ti bẹrẹ, maṣe boju wo ẹyin, Luku 9:61, 62; 17:32; Filippi 3:13, 14

## ALAYE

**Ohun Gbogbo Ni Ṣiṣe**

Nigba ti Jesu pẹlu Peteru, Jakọbu ati Johannu sọkalẹ lati ori Oke Ipalarada, ẹnu ya ọpọlọpọ eniyan gidigidi. Lai si aniani oju Rẹ̀ n dan sibẹ fun ogo ti Baba gẹgẹ bi oju Mose ṣe n dan nigba ti o sọkalẹ lati ori Oke Sinai. Nigba ti O de ọdọ awọn eniyan, Jesu ri i pe awọn akọwe n kó ibeere pa awọn ọmọ-ẹyin, boya nitori ti wọn kò le mu ọmọkunrin kan ti o ni ẹmi yiya odi lara da. Baba ọmọkunrin yii gbe e tọ awọn ọmọ-ẹyin Jesu wa fun iwosan. Wọn ti sa ipa wọn lati le ẹmi eṣu yii jade ṣugbọn wọn kuna. Jesu ba ẹmi aimọ naa wi, a si mu ọmọ naa lara da. "Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin Jesu tọ̀ ọ wá lẹhin, wọn bi i pe, Ẽṣe ti awa kò le lé e jade? Jesu si wi fun wọn pe, Nitori aigbagbọ́ nyin ni: lõtọ ni mo sá wi fun nyin, Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́ bi wóro irúgbin mustardi, ẹnyin o wi fun òke yi pe, Ṣi nihin lọ si ọ̀hun, yio si ṣi; ko si si nkan ti ẹ ki yio le ṣe."

Igba pupọ ni a gbọ pe "ohun gbogbo ni ṣiṣe fun Ọlọrun," ṣugbọn Jesu sọ bayi pe, "Bi ẹnyin ba ni igbagbọ. . . ko si si nkan ti yio ṣoro fun nyin."

**Ọna Igbagbọ**

Ọpọlọpọ ni o fẹ wu Ọlọrun nipa ẹṣẹ, ṣugbọn nipa igbagbọ ni Abrahamu fi wu Ọlọrun. Jesu wii pe, "Eyi ni iṣẹ Ọlọrun pe, ki ẹnyin ki o gbà ẹniti o rán gbọ́" (Johannu 6:29). "Olododo ni yio yè nipa igbagbọ́" (Heberu 10:38). Bawo ni a ṣe le ni igbagbọ ni ibeere ti o wa lọkan ọpọlọpọ eniyan. Bi ohunkohun ba wa lọkan rẹ ti o n de e lọna, bi ohunkohun ba wa ti o yi di ọna orisun ti ibukun yii gbe n ṣan, olootọ ni Oluwa, yoo tu aṣiri rẹ̀ yoo si jẹ ki ohun naa ti o n dena igbagbọ di mimọ fun ọ. Ohun ti o n daamu ọpọlọpọ ni pe wọn ko rin ninu imọlẹ ti Ọlọrun tan si ipa ọna wọn. Nigba ti Ọlọrun ba ran otitọ ọrọ Rẹ sinu ọkan wọn, wọn a maa ro pe ẹlomiran ni o n bawi, wọn ko gbagbọ pe o n ba wọn wi pẹlu. Igbagbọ n wa nipa gbigbọ Ọrọ Ọlọrun, bi a ba pinnu lati mu ohun ti a gbọ ṣe.

**Di Odi Mu**

Lẹyin ti O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ wi pe nitori aigbagbọ wọn ni kò jẹ ki wọn lè lé ẹmi aimọ naa jade, Jesu wi pe, "Ṣugbọn iru eyi ki ijade lọ bikoṣe nipa adura ati awẹ." Eyi fi han wa pe ẹni ti o ba ni igbagbọ ki i sọ ireti nu bi adura ko ba gba lẹsẹkẹsẹ, ṣugbọn yoo gbẹkẹle Ọlọrun sibẹsibẹ gẹgẹ bi Abrahamu ti "ko fi aigbagbọ ṣiyemeji ileri Ọlọrun; ṣugbọn o le ni igbagbọ, o nfi ogo fun Ọlọrun; nigbati o sa ti mọ dajudaju pe, ohun ti on ba ti leri, o si le ṣe e. Nitorina li a si ṣe ká a si ododo fun u" (Romu 4:20-22).

**Awọn Ara Samaria Ẹlẹtanu**

Nitori ẹtanu wọn, awọn ara Samaria sọ anfaani ti wọn ni lati gba Jesu gbọ nu. Obinrin ti o wa sibi kanga Jakọbu sọ ohun ti o wa lọkan awọn ara Samaria. Awọn baba wa sin lori oke yi." Lai si aniani eredi ti awọn ara Samari fi kọ Kristi ni pe, O n kọja lọ si Jerusalẹmu, ko si tẹsẹ duro lati sin lori oke awọn ara Samaria. Ọpọlọpọ lode oni ni o jẹ ki irohin eke ati ohun ti ọrẹ wọn ro di wọn lọwọ lati gba Ihinrere tootọ. Bi ẹni kan ba jẹ olootọ ti ọkan rẹ si ṣi si otitọ, oun yoo mọ otitọ yatọ, lai fi gbogbo ibi ti a ti sọ fun un nipa otitọ pè.

**Iṣẹ Iranṣẹ Jesu**

Ninu itara wọn fun Oluwa wọn, Jakọbu ati Johannu fẹ pa awọn ara Samaria run, ṣugbọn Jesu ba wọn wi bayi, pe "Ọmọ-enia ko wa lati pa ẹmi enia run, bikoṣe lati gba a la." Ninu iba ọrọ wọṅyi, Jesu sọ ohun ti O wa ṣe li ayé -- Igbala. Ihin ti angẹli ni mu wa ni eyi pe, On ni yio gbà awọn enia rẹ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọṅ" (Matteu 1:21). Aanu a maa ṣe Jesu fun awọn ti o kọ Ọ. Nigba ti wọn kàn An mọ agbelebu. O gbadura pe, Baba, dariji wọṅ, nitori nwọn ko mọ ohun ti nwọn nṣe" (Luku 23:34). Jesu fẹ ki awọn ọmọ-ẹyin Rẹ fẹran awọn ọta wọṅ. Peteru sọ bayi nipa Jesu, "Ẹni, nigbati a kẹgan rẹ, ti ko si pada kẹgan, nigbati o jiya, ti ko si kilọ" (I Peteru 2:23) Paulu jẹri si i pe, "Nwọn gan wa, awa nsure; nwọn nṣe inunibini si wa, awa nforiti i: nwọn nkẹgan wa, awa mbẹ̀bẹ: a ṣe wa ni ohun ẹgbin aiye, bi ẽri ohun gbogbo titi di isisiyi' (I Kọrinti 4:12, 13).

**Isẹra Ẹni**

"Bi ẹnikan ba nfẹ lati mã tọ̀ mi lẹhin, ki o sẹ́ ara rẹ̀, ki o si gbé agbelebu rẹ̀ ni ijọ gbogbo, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin" (Luku 9:23). Nigba ti ẹni kan wi fun Jesu pe, "Oluwa, Emi nfẹ lati ma tọ̀ ọ lẹhin nibikibi ti iwọ ba nlọ," Jesu dahun pe, "Awọn kọ̀lọkọlọ ni ihò, awọn ẹiyẹ oju ọrun si ni itẹ́; ṣugbọn Ọmọ-enia kò ni ibi ti yio fi ori rẹ̀ le." Eyi mu ki ede ti Jesu pe bayi pe, "Jẹki o sẹ ara rẹ" ki o ye ni. Ẹlẹda Ọrun óun ayé Ẹni ti "ohun gbogbo wa fun, nipasẹ ẹniti ohun gbogbo wa" – fi apẹẹrẹ isẹra-ẹni lelẹ nipa fifi Ọrun silẹ, O gbe àwọ̀ iranṣẹ wọ, O si n gbe laarin eniyan. "Ọmọ-enia kò ni ibi ti yio fi ori rẹ̀ le." O rọrun ki aniyan ile, iṣẹ ati awọn nnkan ti ara, ki o gba awọn ẹlomiran lọkan to bẹẹ ti wọn ko ni àyè lati tẹle Kristi.

Paulu kilọ fun ni nipa ohun idiwọ ayé yii, o fi ọmọ-ogun ṣe apejuwe. "Ko si ẹniti njagun ti nfi ohun aiye yi di ara rẹ lọwọ; ki o le mu inu ẹniti o yan a li ọmọ-gun dun." O gba lati yọọda ayẹ wa fun Ọlọrun ki a to le di Onigbagbọ. Lẹyin eyi a ni lati maa kú lojoojumọ -- a ni lati maa sẹ́ ara wa ki a le wà lọna naa dopin.

**Ọlọrun, Ṣiwaju Ohun Gbogbo**

Si ipe yii pé, "Mã tọ̀ mi lẹhin," ẹni kan dahun pe, "Jẹ ki emi ki o kọ́ lọ . . . . .". Bayi ni ọpọ ti o gbọ́ ipè Ọlọrun n ṣe. Wọn wi pe, "Jẹ ki emi kọ ṣe eyi, tabi eyi ni, lẹyin naa n o wá sin Ọlọrun." Ọlọrun fẹ ki a fi ti Oun ṣiwaju, ki Oun si leke ninu ọkàn wa. Aṣẹ Rẹ̀ ninu Majẹmu Laelae ni eyi pe, "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi." Awọn Ọmọ Israẹli rú ofin yii nigba pupọ wọn si sin oriṣa. Otitọ ti o wà nibẹ ni pe, ọpọlọpọ ni o n rú ofin naa lọjọ oni ni gbigba ilepa ohun igba isisiyii laayè lati leke ninu ọkàn wọn. "Ṣugbọn ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀."

Gẹrẹ ti o ba ti wa lọna naa, tẹ oju rẹ mọ́ opin ki o si fi ere ti ó wà lopin ọna naa si ọkàn rẹ. Bi o ba bẹrẹ si boju wo ẹyin ti o si n ranti ohun wọnni ti o ti fi silẹ, ẹsẹ̀ rẹ yoo yẹ̀ kuro loju ọna iwọ yoo si padanu. Wiwo ẹyin a maa sọ ni di alaiyẹ fun Ijọba Ọlọrun. Fi ara mọ Paulu ti o wi pe, "Emi kò kà ara mi si ẹniti ọwọ́ rẹ̀ ti tẹ̀ ẹ na: ṣugbọn ohun kan yi li emi nṣe, emi ngbagbé awọn nkan ti o wà lẹhin, mo si nnọgà wò awọn nkan ti o wà niwaju, Emi nlepa lati de opin ire-ije nì fun ère ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:13, 14).

**AWỌN IBEERE**

1. Ṣe apejuwe iru ipò ti ọmọkunrin ti a mẹnukan ninu Matteu 17:15 wà.
2. Ki ni mu un dé ipò naa?
3. Ki ni ṣe ti awọn ọmọ-ẹyin kò lè wò ó sàn?
4. Ki ni Jesu sọ pe a le ṣe bi a ba ni igbagbọ́?
5. Iru ọkàn wo ni Jakọbu ati Johannu ní sí awọn ara Samaria ti kò gba Jesu?
6. Bawo ni ọkàn Jesu ti rí sí awọn ara Samaria?
7. Ki ni idahun ti Jesu fi fun ọkunrin ti o wi pe "Emi nfẹ lati ma tọ̀ ọ lẹhin nibikibi ti iwọ ba nlọ?"
8. Ki ni itumọ ede ti Jesu pe bayii pé, "Jẹ ki awọn okú ki o mã sinkú ara wọn?"
9. Ṣe alaye iwa awọn ọkunrin mẹta ti a sọrọ wọn ninu Luku 9:57-62.